# “ko si irun pẹlu ikalẹ ounjẹ, tabi nigba ti igbẹ ati itọ ba n gbọ̀n ọ́n”

Lati ọdọ ‘Aaisha- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Dajudaju mo gbọ́ ti ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe: “ko si irun pẹlu ikalẹ ounjẹ, tabi nigba ti igbẹ ati itọ ba n gbọ̀n ọ́n”.
[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- kọ kuro nibi kiki irun pẹlu ikalẹ ounjẹ ti ẹmi olukirun n fa síbẹ̀, ti ọkan rẹ si n so mọ ọn. Gẹgẹ bẹẹ ni o ṣe kọ kuro nibi kiki irun pẹlu dídá Al-Akhbathaan- awọn mejeeji ni itọ ati igbẹ- padà, nitori kiko airoju rẹ pẹlu dídá ẹgbin náà padà.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3088

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee